"AIYE NLỌ, A NTỌ Ọ

NIGERIAN SECRETARIAT 28 SEP 1931 LAGOS

# AKEDE EKO.

LATI KEDE ANU FUN AWỌN OTOṢI ATI MẸKUNU, ATI LATI GBA AWỌN OJIYA ENIA KURO LỌWỌ IDAMU AWỌN ALAGBARA

VOL. IV. No 38 SATURDAY, September 26, 1931. THREEPENCE.


S C O A

## S.C.O.A.

S C O A

S C O A

## SOCIETE COMMERCIALE DE L'OUEST AFRICAIN

152 156, BROAD STREET,
121, VICTORIA STREET,
144, VICTORIA STREET,
3, DENTON STREET, EBUTE-METTA.
ABẸOKUTA (IBARA ROAD).

***SELLS EVERYTHING***

**To Meet Every Body's Purse.**

Provisions
Cottons
Hardware
Drugs.

Best Quality
Lowest Prices
Quick Attendance

***Have a Trial***

AND

**You will become our regular customer.**

AWA NI ONIṢOWO TI YIO FUN NYIN L'ERE PUPỌ LORI OJA

S C O A

S C O A

## S.C.O.A.

S C O A

# MESSRS: J. H. DOHERTY,

**LIMITED,**

## INVITE YOU

TO INSPECT THE LARGE RANGE OF NEW MATERIALS IN THEIR NEW BROAD STREET STORES:

## *Included in which are:*

Newest and Finest Shades and Designs
LADIES' DRESS MATERIALS, LADIES READY-MADE DRESSES, AND GENTLEMEN'S SUITINGS.

**Do Not Fail To See Our**

**Ladies' and Gentlemen's Hats, Shoes, Hosiery, etc.,**
Ladies Underclothing of all kinds,
Gentlemen's Shirts, Ties, and Pyjamas.

Beds, Beddings, Hardware, Cutlery Crockery, Chairs, Tables, Picture Frames Suit Cases, Fresh consignments every steamer.
Gramophone and Gramophone Records. Humber Cycles by instalments.

COME ONE! COME ALL!!

***Lowest Prices*** ***Highest Quality.***

P.O BOX NO. 140, LAGOS. PHONE 182, LAGOS.

## ṢABU "OGA NI DUHATI."

Ẹnyin Ọmọge Alalẹ, l' ọkunrin ati l' obinrin, eti nyin melo? Ki gbogbo ẹnyin ara ile y' ara tanṣẹ sọ fun awọn ara oko wipe ko ṣe rọ ni ti Ṣabu ṣe ran'wo "ỌGA NI DUHATI" ti a npe ni **MESSRS: J. H. DOHERTY, Ltd.,** ti nwọn ṣẹṣẹ ṣi ni rẹpẹtẹ s' ọna opopo nla Broad Street, l' ode Eko, nisisiyi.

Awọn ojulowo-aṣọ atata fun ọkunrin ati fun obinrin l' agba ati l' ọmọde lo pe'ju si Ṣabu na ṣiba; awọn ohun ọṣọ fun awọn ọmọge-alafẹ nṣubu lu ara wọn; ọpọku-ọyọku si ni owo ọja wọn na fun tita.

Ki gbogbo ẹnyin enia y' ara lọ ra awọn ọpọ ọja to nṣe ojulowo l' ọdọ awọn ile iṣ'owo **Messrs: J H. Doherty, Ltd.** yi, nitoripe ko ṣe rọ ni gbogbo awọn ọja to mbẹ ninu Ṣabu titun yi jẹ.

Ẹnyin ero idalẹ le kọ'we pẹlu owo ṣ' ọwọ fun ọja ti ẹ ba fẹ ra lati inu ile-ọja:

**MESSRS: J. H. DOHERTY, LIMITED,**
*Broad Street, Lagos, Nigeria.*


[Awọn ẹnikẹni ti nwọn ba ti ipa ọdọ wa de ọdọ awọn Oniṣowo "Pambabari" yi, ki(nwọn da oruko iwe irohin "**AKEDE EKO.**"]

**DRINK NOTHING WITHOUT SEEING IT; SIGN NOTHING WITHOUT READING IT. AND MAKE SURE THAT IT MEANS NO MORE THAN IT SAYS.**

## OLOFINTOTO

——:o:——

### NSI YIO HA GBA WA BIKOṢE IWỌ NIKAN-ṢOṢO OLODUMARE, L'ỌWỌ OWO-ORI—ESU-A-DA-IKO!!!

Lati ọdun 1927 ni gbogbo Ilu ti wọru owo ori ni sisan fun Ijọba, inira ọpọlọpọ ni san owo na si jẹ; ẹlomiran ni ọmọ wẹwẹ bi meji tabi mẹta, ki o to bọ awọn ọmọ wọnyi, ki o to d'aṣọ fun wọn, bẹni o lati fi wọn si Ṣukuru, lẹhin ti o ba jaja san Ṣukuru tan, owo Ṣukuru ti kuro ni ọwọde nisisiyi, o ni lati bọ ṣokoto giri nitoripe ni ọjọ ti Ijọba ba pin iwe owo ori fun u, larin ọgbọn ọjọ o ni lati san ṣile mẹfa, mẹwa, tabi pọwun kan fun Ijọba. Ẹlomiran iṣẹ ti o nṣe ko to fun bukata ara rẹ ẹpo bukata Ọba, ṣugbọn tulasi, o ni lati wa owo yi ri; aidọgba ko si ṣai wa ninu owo aisan. Bi ẹlomiran ba jẹ Carpenter, o ni lati san ṣile mẹwa, boya ko ri pọun kan gba l'oṣu, boya apoti oni ṣile meji-abọ lo ri kan, ṣile kan pere lo si ri gba ni owo ilelẹ. Alaru (a labourer) ni lati san ṣile mẹfa, Alaru ti o ri owo gba ju kọbọ mẹwa ojumọ ṣọwọn. Inira ọpọ ni owo ori yi jẹ fun enia ati wahala fun Ijọba pẹlu, nitoripe a ko ṣai ri awọn akọwe olowo ori ti Ijọba mba se ẹjọ pe wọn gbowo na lọna eru ninu oṣu ti o kọja yi ni awọn Ọlọpa ba ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Isaac Fawibẹ ṣe ẹjọ pe o gba ṣile mẹfa lọna eru ati pe o jẹ onişẹ-ọba o fi ṣile mẹfa owo ọba ṣe ti ara rẹ; Ọrọ yi kuro ni yẹyẹ, o di ọran kotu ti Ọga Oloworinsọ ni Kotu ohun ti o jẹ iṣẹ awọn akọwe olowo-ori wọnyi, ati pe, Ijọba ko ran awọn akọwe wọnyi lati gbowo kiri, ọrọ ti a nwi yi akọwe yio lọ si Kotu l'ọjọ yi to mẹta tabi ju bẹ lọ lati ri iṣẹ Aṣoju.

Isaac Fawibẹ, akọwe owo-ori ti nwọn ba ẹjọ ma gba Lọya ni 'di ṣile mẹfa yi. Ki Adajọ da a silẹ pe ko jẹbi.

Ẹ o wa ri iyọnu ti o wa fun tọtuntosi bayi? a ṣeṣẹ le ma sọ ti ẹniti o sanwo mọ. Inu Ilu yio dun bi Gomina wa Oyinbo "Kaiyero" ba le ba wa din owo na ku si ṣile meji-abọ nitori ode le papọ.

### "A KI NṢE ỌRẸ ERO K'AYỌ, ERO NRE'LE RẸ L'ỌLA."

Ninu iwe irohin wa yi l'ọsẹ to kọja ni a rohin pe Ọgbẹni Isaac B. Thomas, Olotu iwe "Akede Eko" yi ati iyawo rẹ mbẹ ninu irin-ajo wọn lọ si Ijẹbu-Ode ati yika Arọ'ko ilu awọn Ijẹbu, ṣugbọn nisisiyi, awa tun ni anfani lati tun jihin fun ẹnyin onkawe wa wipe gbajumọ *Editor* wa na ati iyawo rẹ pẹlu Ọmidan Abigail Ogunniyi, Akọwe obinrin ti "*Akede Eko,*" ati William to nṣe ọmọ ọdọ nwọn pelu jumọ pada de s'Eko nisisiyi lati ọna irin-ajo wọn na.

Lapakan iwe irohin wa ọjọ oni, ni ẹnyin ọkawe yio ri irohin irin-ajo *Editor* na ka l'apẹ Ero Ọna. Ẹ k'abọ o, ẹnyin Ero l'Ọna! !

### "KO ṢẸHIN OLUWA," TABI IWE AROFỌ—ALADUN.

Awa ṣ'ọpẹ pupọ l'ọwọ Ọgbẹni Afolabi Johnson fun Iwe Aladun rẹ titun kan ti gbajumọ ọdọmọkunrin na fi ta wa l'ọrẹ orukọ Suno iwe onigbadun na a ma jẹ "Ko Ṣẹhin Oluwa at awọn Arofọ Miran." Ṣile kan pere ni nwon nta iwe iyebiye na; iwe to yẹ ki gbogbo ọmọ ibilẹ Yoruba ni l'ọwọ ni Iwe Arofọ na nṣe.

Aje a ma wọ 'gba wa o, Afolabi Johnson, Akere-koro ninu Arofọ Ọpẹlẹngẹ kiki ọgbọn l'ori Ọdọmọde-kunrin.

---

### ORIN FUN ỌGBẸNI ISAAC B. THOMAS,
### Editor "Akede Eko,"
### NI IGBORO ILU IJẸBU-ODE
### (NO 1.)

*( Lati ọwọ Gbajumọ Akọrin Ijẹbu-Ode )*

| SI ONIWE IROHIN AKEDE EKO. | OHUN ORIN BIṢI LA O FI KỌ ORIN NA. |
|---|---|

MO JUBA O,

(1) Ẹ ku idide ijẹun
Bẹ ba de'le Thomas kẹ ba ni ki i,
Bẹ ba de'le Thomas kẹ ba ni ki i!
Nijọ to de Jẹbu gbara ọba wa ṣariya titi
O dun mọ gbogbo wa d'opin
O dun mo gbogbo wa d'opin
Akede Eko ṣ'alafia lẹ ba wọn n'ile e?
Gbogbo Ẹgbẹ Onirohin ṣe Thomas ni baba wọn,
Oluwa lo fun u l'agbara, oro aiye,
Oluwa lo fun u l'agbara, oro aiye
Ẹgbẹ Onirohin kẹ papọ sibikan
Ara Eko ka fi Thomas ṣ' olori.

(2) Ma f'orin ṣe bukun fun ẹ
"Akede Eko" Ọlọjẹ mo ri si ti wọn
"Akede Eko" Ọlọjẹ mo ri si ti wọn
Ninu iwe Onirohin t'Akede Eko ja fafa
Ki t'ẹru, t'ọmọ f'ọwọ si i,
Ki t'ẹru, t'ọmọ f'ọwọ si i
Ma f'orin ranṣẹ re 'Lesha ma sọ fun wọn gbọ
Ẹ jẹ ka tẹ'wọ gba'we irohin Akede Eko tita de'Ado
Ma lọ sọ fun wọn ni Rẹmọ, oro aiye
Ma lọ sọ fun wọn ni Rẹmọ, oro aiye
T'Eko t'Ijẹbu kẹ fi 'dahun si i,.
Akede Eko o, onigege adun ni wọn jẹ!

### (OHUN ORIN ẸFẸ LA O FI KỌ ORIN KẸTA YI.)

A to ba ṣire Thomas, ma lọ rohin f'Awujalẹ
A to ba ṣire Thomas, ma lọ rohin f'Awujalẹ
Sanmọri ara Eko o. Thomas lo l'ori yẹ fun u
Ẹnyin Otẹwe o, ṣe Thomas lo to fun baba a
Ẹnyin Otẹwe o, ṣe Thomas lo to fun baba a!

*AKIYESI:*—Awọn orin mẹta oke iwe yi ni awọn orin ti gbajumọ Akọrin pataki kan ni igboro ilu Ijẹbu-Ode fi dabira nipa bibẹwo ti Ọgbẹni Isaac B. Thomas, Editor Akede Eko yi lo bẹ ilu Ijẹbu-Ode wo l'ojọ aipẹ yi. Ninu iwe irohin wa yi l'ọsẹ to mbọ l'agbara Baba ni a o tun tẹ awọn orin aladun ti Akọrin kanna yi kọ nipa Afinju ọba Eṣugbayi Eleko ati Ọgbẹni Herbert Macaulay, C.E.

"ARABA NI BABA, ẸNITI A BA L' ABA NI BABA ẸNI."

ILANA ETO ẸGBẸ.

## Nigerian Mercantile Bank.

***Limited.***

**Head Office:**

LAGOS, NIGERIA.

TI A DA SILẸ NI NIGERIA NI ỌJỌ KỌKANDILOGUN, OSU MAY, 1931.

## Awon Amona Egbe

The Hon. Dr. Dr. Curtis Crispin Adeniyi-Jones, M.B., CH.B., Pricilla Hall, Lagos.
*First Lagos Member of the Nigerian Legislative Council,*
*Chairman, Nigerian National Democratic Party,*
*Chairman of Directors, Nigerian Medicine Stores, Ltd.*

Winfried Tete-Ansa, Esq.,
*Life Fellow of the Empire Royal,*
*Director of Companies*
98, Broad Street, Lagos. Nigeria, and Castle Road, Christianborg, Accra, Gold Coast

Dr. Akinọla Maja, M.B., CH.B.,
*Director, Nigerian Medicine Stores, Ltd.*
*Director, Oshodi and Apena, Ltd,*
41, Layẹni Street, Lagos, Nigeria.

Joseph Mọdele Cole, Esq.,
*Contractor,* 25, Kopada Lane, Lagos, Nigeria

**Registered Offices:**
98, Broad Street, Lagos, Nigeria, West Africa, P.O. Box 553.

**Managing Director:**
Mr. W. Tete-Ansa, Director of Companies, 98, Broad Street, Lagos, Nigeria.

**Solicitor:**
Mr. W. Wells-Palmer, Barrister and Solicitor, Wilberforce House, Lagos, Nigeria.

**Secretary-Accountant:**
Mr. Dan. D. Quist, 162, Bamgboṣe Street, Lagos, Nigeria.

**Auditor:**
Mr. Hauzat Subair, Accountant, 10A, Bishop Street, Lagos, Nigeria.

IWE IFỌWỌSI KI ẸNIKẸNI TO LE WỌ ẸGBẸ IFOWOPAMỌ (BANK)

NIGERIAN MERCANTILE BANK LIMITED.

*(Ti a da silẹ ni Nigeria gẹgẹbi Ẹgbẹ)*

Iye Owo (Capital) ti a fi bẹrẹ Banki yi jẹ ẹgba-marun pọun, (£10,000)

SI AWỌN OLOTU ẸGBẸ BANKI.—

**NIGERIAN MERCANTILE BANK LIMITED.**

Ẹyin Bọkini;

98, Broad Street, Lagos Nigeria, P.O. Box 553.

Mo san £ ........fun owọ........ninu ipin ti oni ṣile marun-marun [5/-] fun ẹnikọkan ti a npe ni **Preferred Share** ninu Banki yi, mo si torọ gafara pe ki ẹ yọda iye owo na fun mi mo gba pa ng o gba iye na, tabi bi ko tile to iye na gẹ bi Eto ati Ilana Ẹgbẹ nyin, mo si fun nyin ni agbara lati fi orukọ mi sinu Iwe orukọ awọn Ọmọ Egbe Ifowopamọ ni iyẹ owọ ti a yọda fun mi.

Bi emi ti ima kọ orukọ mi nigbagbogbo.............................. Orukọ mi ni kikun. ..............................

[Sọ bi Mr. Mrs. tabi Miss ni] Orukọ ibiti mo ngbe.................... Iṣẹ ti mo nṣe..............

Ọjọ ti mo fi owọ sii iwe yi................

**Akiyesi:**—Ẹniti nlẹ wo Ẹgbẹ yi le ṣe eto bi ẹnikẹni ti n alsan owo iye owọ ti oko diẹdiẹ nigbamiran, a si le gba ọja bi a le ṣe dipo owo-yowo.

" BA 'NU SỌ, MA B'ENIA SỌ, ENIA KO SI MỌ, AIYE TI D' EKE."

*Editor & Proprietor:—*
ISAAC B. THOMAS,

*Editorial Office:*—47, Bamgboṣe Street, Lagos
P.O. Box No. 646,
Lagos, Nigeria.

**Telegraphic Address.**
"KEDE-EKO" Lagos

*ORIN:—Li ọnak'ọna, "Oluwa y'o pese"*
*O le ṣ'aṣ'ọna mi, o le ṣ'aiṣe ìrẹ,*
*Ṣugbọn l'ọna'ra Rẹ, li On o pese!*

*Ma bẹru, lori "Oluwa y'o pese"*
*Eyi n'ileri Rẹ, kọ s'ọrọ ti O sọ*
*Ti si yipada, "Oluwa o pese".*

# Akede Eko

EKO, SATURDAY, September 26, 1931.

## AIYE NLỌ, A NTỌ Ọ.

Ko si bi o ti ri ni ode isisiyi; gbogbo aiye ni a ngbọ ti enia nke pe 'ode le', o tilẹ dabi ẹnipe ni ọdọ wa nihin, ode na san diẹ Ki Oluwa ma jẹ ki o le ju eyi lọ fun wa o—Amin.

Ni ọdun melo kan s'ẹhin ni asiko owo Kọrẹnsi (Currency Notes) ni asiko Koko (Cocoa), ya a ni a nṣe owo. ti a nna ina-ku-na, apa ko ṣa mọ pe ohun ti o pọ, o mbọ wa tan. A nṣe owo ni iṣekuṣe, a na a ni ina-kuna Awọn ẹlomiran nwọn a mu awọn paper Kọrensi oni Pọun kọkan, nwọn a fi we Siga (Cigar) nwon a si bẹ ina si i. Ni asiko kan a gbọ pe Olowo igànmọ kan tilẹ da a l'aṣa nigbati o yo tan, o nfi Kọrẹnsi oni Pọun kọkan ko ina ẹja ti wọn ndin fun u lati jẹ.

Obinrin kan sọ fun wa lasiko kan pe, ọdọmọkunrin kan ko on l'ọna ni ijọ kan, o si ba on s'ọrọ pe on fẹ fẹ on, bi o si t. sọrọ tan ni o yọ *Cheque* iwe-owo-Banki ni o kọ ọ, ni o si fi le on lọwọ pe ki on ṣi gba iyẹn na, ki on lọ ro ọrọ na wo ki on to wa fun on l'esi; pe bi ere, bi ere ni on fi lọ si Banki ni ọjọ keji, ti wọn si ka Ọgbọn Pọun (£30) le on ọwọ, ti on si ṣbojuwo ẹhin titi on fi de ile, ti ẹnikẹni ko se on wo titi on fi wọ'le ti on si fi owo yi pamọ. Ẹ o ri i, bi ọpọlọpọ wa ti ṣe na owo ọpọ niyi, Ki Ọlọrun ma fi ẹṣẹ wa bi wa o—Amin.

Nisisiyi, ode le, o le korokoro bi oju ẹja, ẹniti o ba si ri nkan kan dimu, o yẹ ki o di i mu ṣinṣin, ko fi ọwọ mejeji di i mu, bi o ba si gba bẹ ki o fi ehin di i mu pẹlu.

O yẹ ki olukuluku wa k'ọgbọn ni ode isisiyi, ki a kọ bi bi a ti nṣọ ohun ini wa lo; ẹlomiran wa, hova nigba kan ri, ko jẹ jẹ ẹba (ọka) ti ijọ keji, ṣiṣe ini ... ṣi i danu, ṣugbọn nisisiyi pẹlu ayọ ni ... jẹ ẹba ijọ kẹrin bi o ba ri i. Nitorina, jẹ ki olukuluku wa kọ lakoko yi, bi a nlo ohun gbogbo lo jasi tiwa, ki a ma ilokilo, ṣugbọn ki a ma fi ọgbọn ati ẹtọ ohun gbogbo ti a ni, ti ko fi ni le ni wa ninu ode ti o le yi, ki a si ma ranti ... gbogbo pe—

*"Alagbara ma m'ero, baba ọlẹ ni"*

Aiye nlọ, a ntọ o. Ni akoko kan ... enia ba ri iṣẹ, ti a ba si sọ fun u pe bayi ni ao san fun u, yio kọ, yio ... pe iye bayi ni on nfẹ gba, bi bẹkọ ... wa iṣẹ ti on lo si ibomiran; ṣugbọn ... enia mbẹbẹ pe ki a tilẹ gba on si iṣẹ, ... kọ iye-kiye ti wọn o ba san fun on, ... ko ri. Ode na ko ha le nitotọ bi?

Nisisiyi, airi iṣe ṣe pọ ni ilu, ki ṣe ilu wa nihin nikan, ṣugbọn ni gbogbo ... ni, awọn oyinbo lo si ma npowe kan ...

"*Necessity is the mother of invention*" eyini ni pe "*Iṣẹ ni'mu ọmọ jọ'gbọn*" tabi "*Ebi kọ were l'ọgbọn*".

nitorina, ni a ṣe fẹ ke si gbogbo ẹnyin ... wa ti o jẹ pe koiti ri ibi iṣẹ kan ... ni akoko yi pe, bi a ba dẹ'ju silẹ, ao ... eyini ni pe bi a ba fi ara balẹ wo ... wa, a ko le ṣai ri iṣẹ wẹ-wẹ-wẹ ti a le ... owo pa ti yio si ma mu Okan, Eji, ... wa, ti ao ma fi jẹun; bi ọrọ ebi ba ṣa ... ninu iṣẹ, eyiti o ku fuyẹ.

Ẹ jẹ ki gbogbo wa ke si Baba wa ... l'Ọrun ki O ma ṣai tete pa igba ode lile ... rere fun wa, ki ara le tu wa, ki ara ... wa, ki ara le dẹ wa, nigbati o ba si ... fun wa tan, ki a ma gbagbe Baba Ọ... na to ṣe eyi fun wa, ki a ma si ... lati fi ran awọn ọmọ ẹnikeji wa l'ode ... lọwọ, ati lati fi ṣ'ore fun ilu wa pẹlu.

Ki Ọlọrun pa igba da si rere fun ... wa—Amin Aiye nlọ, a ntọ ọ.

---

### BURAIMỌ ARO, ẸNITI A BA TA KI ... R'ATUPA, ALAKORI KAN NINU IWE ... "*THE NIGERIAN DAILY TIMES*" NI ... AJITANA WO L'ORU.

*(Lati ọwọ Balogun Dodondawa)*

Ologbe Alufa M. L. Stone ti o npe ara rẹ ... okuta," lo nṣe kilọkilọ ni sa a kan fun ... pe ki nwọn tete fi iwa ibajẹ ọti mimu silẹ ... nigbati wọn ba jingiri sinu rẹ tan, ... ti "Ọti, ọti, bi o lo o mu mọ, a si ma ... ọti, ọti,

Bẹ gẹgẹ ni ọrọ iwe k.kọ si iwe irohin ... ilu ẹni. Bi o lo o kọ mọ, a si ma a ... iwe, fun ire ilu ẹni.

Gbogbo ẹnyin ọkawe wa ni yio ṣe ... ko pẹ pupọ lẹhin ipade bọwale ọba wa ... Eṣugbayi Eleko nigbati a da ọwọ kiko iwe ...

**"I'LL NOT BEAT THEE, NOR ABUSE THEE, BUT I'LL GIVE THEE AN ILL NAME."**

tẹ'wọ gba wa ni alejo si ile rẹ na, bakanna pẹlu si ni Opẹlẹngẹ ajirera Mrs. Otubaṣin si fi ifẹ-inudidun rẹ ṣikẹ on igẹ wa pẹlu, bayi ni ilẹ ọjọ kini oni ninu irin ajo wa yi ṣu wa si igboro ilu Ijẹbu Ode; orun-arẹ irin ọna ti a si sun mọ'ju ọjọ keji jẹ eyiti o kun fun igbadun pupọpupọ.

"Wọ Imọlẹ larin okun aiye,
M'a sin mi lọ
Okunkun ṣu mo si jina s'ile;
Ma sin mi lọ.
Tọ' ṣisẹ mi: ohun ẹhin ọla
Emi ko' bere 'ṣisẹ kan to fun mi."
Iyoku di ọsẹ to mbọ lagbara Jehovah!

## APPRECIATION.

Mr. and Mrs. Isaac B. Thomas, Editor and Proprietor of this popular Bilingual newspaper, the "*Akede Eko*", beg to place on record their heartfelt t h a n k s and grateful acknowledgments of the many favours and hospitalities kindly lavished on them both individually and collectively during their last tour of Ijebu-Ode a n d Province, which favours had severally and invariably contributed considerably to ameliorate the difficulties and inconveniences usually incumbent on such an itinerary undertaking.

In this connection they would specially mention the names of His Highness the Dagburewe of Idọwa via Ijebu-Ode, His Highness the Awujale of Ijebu Ode; Mr. & Mrs. D. R. Otubuṣin of Ijebu-Ode (their host and hostess); Rev. & Mrs. I. O. Ransome Kuti of Ijebu-Ode, Rev. and Mrs. S. E. O. Ṣoyẹmi of Imushin via Ijebu-Ode, Rev. and Mrs. D. Ogunbanjọ of Iṣọnyin via Ijebu-Ode. Rev. & Mrs. D. A. Fawẹhinmi (their host and hostess) at Ọjọwọ, Ijebu-Igbo via Ijebu Ode Chief Orimolusi of oke Jaga via Ijebu Igbo, Rev. and Mrs. D. A. Beckley (their host and hostess) at Agọ via Oru & Ijebu-Ode; Mr. and Mrs. G. S. Oduwọle (their host and hostess) at Shagamu and also Rev. and Mrs. S. O. Mafẹ at Shagamu.

Mr. and Mrs. Isaac B. Thomas would also always fervently pray that the God of Grace may bless them all abundantly out of the stores of the riches of His goodness.

*Ẹ ku ina'wo ọjọ, abusi Baba lati Oke wa o!*


**Cement "Enci"**

best quality
Quick hardening

Apply:—J. F. Sick & Co.,
5, Customs Street. Lagos.


## PUBLIC NOTICE.

In honour of the Eleventh Anniversary of the Coronation of

**His Highness ADEMOLA II,**
The Alake of the Egbas

The following Programme is published for general information:—

**Saturday, 26th, of September:—**

**Cenema Show**

at the Abẹokuta "**Centenary Hall,** when Centenary Celebration Pictures will be exhibited at 8.30 p.m.,

**Sunday, 27th, September, 1931:—**

**Thanksgiving Service**

at St. Peter's Church, Ake, at 10 a.m., when Special Sermon will be delivered by

**Rev. E. K. Ajayi-Ajagbe.**
Suprintendent, Wesleyan Abẹokuta Circuit.

A procession, consisting of the Alake, the Obas and other Members of Council Ogboni and Ologun Chiefs and other prominent men in the Community, will be formed from the Palace, Ake, to St. Peter's Church, Ake at 9 30. a.m. precisely.

**ALMS TO THE POOR**

will be distributed at the Alake's Square, from 8 30.,—9 a. m.

**Monday, 28th, of September, 1931:—**

**Sports for the School Children**

at the Alake's Square, at 3 30. o'clock p.m., when Prizes will be distributed to the winning Competitors.

A GRAND

**Concert and Dance**

will be given at the Abẹokuta Centenary Hal at 8 30 p. m., by the

**ABEOKUTA AFRICAN RECREATION CLUB.**

ADEGBITẸ ṢOBỌ,
*Asoju Oba.*

Ake, Abeokuta,
16th, September, 1931.

"AGBA TI KO BI 'NU NI ỌMỌ RẸ NPỌ"

## CORRESPONDENCE.

### "WEST AFRICA"

### The Change of Ownership.

It was made known in London during the latter part of August that the Weekly Newspaper "West Africa" had changed hands—or rather, changed ownership, for it remains in the same hands, editorial and commercial, in which it has been from its first number, published nearly 15 years ago.

Some time ago an offer was made for the whole of the share capital in the paper (nearly £11,000). It is understood that the offer was made on behalf of the Liverpool and London firm of printers and advertising contractors which acquired the monthly "West Africa Review" some months ago when Messrs Elder Dempster & Co. ceased to own it. At meetings between the Editor of "West Africa" and the shareholders it was made clear that the owners of the majority of the shares felt that as a sale was to take place—a few shareholders wishing to sell the proper course was for the staff itself to buy the entire property, and give an undertaking that the paper should for a period of years be in the hands of its staff alone, the shareholders in turn agreeing not to interest themselves financially for a similar period in any such publication as West Africa in England. This proposal the staff accepted. A new company was formed, with the same name, and from mid-August the new owners have carried on the business. The paper's name is, of course, unchanged.

The "Times" of August 29 in a reference to the sale states that the senior members of the editorial and business staffs have held their posts since the paper's first publication, and that the paper's editor and founder, Mr. Albert Cartwright, remains in editorial charge and becomes chairman of the company. The "Newspaper World", the old, well-known organ of the British newspaper industry, says that the price paid by the staff was 25/- per share, the same figure offered by the outside quarter; and that of this 25/- about 20/- per share was in hand, in the shape of accumulated profit, when the staff took over. The "Newspaper World" recalls that "Twenty Years' Fleet Street Free-Lance" recently remarked of "West Africa" in a Volume of reminiscences, that "it is known as the 'Times of West Africa' and is famous for the courage and independence of its views and the splendid way in which photographs are reproduced." In another English journal it is remarked that "West Africa's" photographic pages have given people in Great Britain quite a new view of the four Coast Colonies.

### The Life History of Me, Segilola, Endowed with fascinating eyes, the sweetheart of a thousand and one men.

CHAPTER 14.

To the Editor,
Akede Eko.
Dear Mr. Editor,

I am now going to relate the preparations which I was making for my marriage with Bankọle, but before I do so I would like to thank through you one of the readers of your paper called "Jumọkẹ," whose message you delivered to me that she gave you ten shillings as a present to me and you brought the money personally to me one Wednesday evening October 2.

Although I refuse to accept the money, yet it was through your soliciations that I received it last. I offered you half of it yourself, but you refused. I am sending the amount along with my letter for the week to pay it into the funds of the "National School for Nigeria" which is proposed now to establish for the benefit of our children accompanied with these words:—

"From Sẹgilọla of the Akede Eko Weekly Journal."

Once more I beg you, dear Editor, to thank your reader "Jumọkẹ" for her kindness, my prayer for her is that God the Rewarder of all may shower His blessings on her from this day and for ever.

I shall ever be greateful if the account of my life as here published does any good whatever to your readers, and if death should now call me away into the presence of God, I shall have no doubt that God will forgive me before His Throne of Judgment.

As I had occupied much space already in your paper I shall defer the narration of the preparations for my marriage till next week God's willing.

I am,
Yours very Sincerly
SẸGILỌLA ELẸYINJU EGE.

---

## IN MEMORIAM.

✠

### GONE ! BUT NOT FORGOTTEN !

In ever loving and affectionate remembrance of my dearly beloved sister:—
**MRS ROSLINA MOSUNMO AUGUSTUS,**
who departed this weary life on Saturday, the 21st day of September, 1929.

"Alas! that one so lovely
Should perish as a flower?
But now! she blooms unfading
In a better land than ours."

We love thee well, dear "**Mosun**," but Jesus loves thee best.

Rest in peace forever!

E. S. CARDOSO.

36, Balogun Street,
Lagos, Nigeria.

# PIRELLI

## THE WORLD'S BEST

THE TYRE

To Suit all Roads and all Conditions.

**Guaranteed never to let you down.**

Obtainable at the Sole Distributing Agents:—

## S. C. I. N.

37, Marina, Lagos.

**And at all Branches throughout Nigeria.**

## ODEON.

**NIGERIAN RECORDS**



*Hadgy MASHHOOD*

NEWLY ARRIVED

on Arabic "ODEON" Records

New Songs on Ęsugbayi Eleko Herbert Macaulay, Chief Oluwa, Tukuru Ajibabi

Records Sung by Abibu Abibus. Ajapę Ilorin, Saka Jeje, Irewolede Denge.

Gramophone Shop **"ODEON"**

**Witt & Busch**

Lagos—Ibadan.

**Obtainable also at Hadgy Mashood, 63, Victoria Street, Lagos.**

**Sole Agents for:** Abęoku'a, Kano, Port Harcourt, Aba, Jos, S.C.I.N., Calabar, J. F. Sick & Co.

# OGUN MẸNTỌLETỌMU,—AWO-'GBA ARUN.

Egbogi Mẹntọletọmu A-jẹ-bi-idan. Ki ẹnikẹni maṣe ṣai! ma ni ogun atata ni l'ọwọ ni ile fun lilo nigba-kugba.

## *Just what you need Mentholatum*




ALL Doctors agree that MENTHOLATUM is needed every day. This wonderful balm has a hundred and one daily uses, nobody can afford to be without it.

MENTHOLATUM possesses the most marvellous Antiseptic and Healing powers; Cuts, Wounds, Burns and Bruises are healed in an amazingly short time. For Insect Bites, Prickly Heat, Sore Feet, etc. it is without equal.

Also the Cool, Soothing Properties immediately charm away all pain and irritation. Nothing is half so good as MENTHOLATUM. Do not be put off with cheap and nasty imitations, see that the word "MENTHOLATUM" is on every jar you buy.

*Sold everywhere in West Africa.*

TRADE MARK

**MENTHOLATUM**

REGISTERED

THE MENTHOLATUM COMPANY, LTD., SLOUGH, ENGLAND

*Over 20 million pots sold last year.*

Ojulowo ogun bi Mẹn-tọletọmu s'owọn pupọ yika gbogbo aiye, ki gbo-gbo enia ma ni Mẹntọle-tọmu owọ ni i nigba-gbogbo nitori-ripe Ẹkun baba ọdẹ si egbogi na fun gbogbo awọn arun ara.

O ju ẹgbẹrin o le adọta-ọkẹ igo egbogi ti a npe ni MẸNTỌLETỌMU lọ ti a nta l'ọdọdun kakiri gbogbo agbaiye, ni gbogbo ilẹ Iwọ-orun Afrika li a si mọ bi egbogi na ti jẹ to.

Ẹgbogi ti a npe ni MẸNTỌLETỌMU yi ni egbogi totọ fun wiwo gbogbo arun ti mba Awọ ja, Ori-fifọ, Otutu-ori, Ara-jijona, Ọgbẹ ati Apa-ọgbẹ.

Gbogbo awọn Dokita ni ilu gbogbo li o nrohin pe egbogi na ni lilo fun t'agba t'ọmọde.

Ri i pe ojulowo MẸNTỌLETỌMU yi ni o ni l'ọwọ ki o ma si ṣe jẹki a ta aiyederu ri nb o.

Printed at "Tika-Tore" Press, 20, Market Street, Lagos and Published by ISAAC B. THOMAS, at 47, Bamgbose Street Lagos